

# EYI NI ỌJỌ AWỌN ỌJA ILẸ WA.

### OJỌ AJE 30TH JULY (MONDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Oyingbo |
| Abeokuta | Ijoko Iberekodo Asa Wasimi |
| Ibadan | Oode Ogunjana Lagun |
| Ijebu | Aiyepe Sasanu Ita-osu Oere Irolu Ita Aganda Ita-Iloti Oru |
| Ijesha | Ilesu-Ilesha Imodi Ibode Kajola, Oluwa'da |
| Ondo ati Eti Odo | Anigi Aiyetoro Oka Ilara Epe |
| Egbado | Alagba Ilaro Sunwa Iboro |
| Ogbomosho | Obada Gambari |
| Ekiti | Ilogbo Oke-Aiyedun Idogun |
| Ibinni | Eke |
| Delta | |
| Igbajo | |

### OJỌ IṢẸGUN 31ST JULY (TUESDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Obun-Eko |
| Abeokuta | Atan Agbado Ifo Itoko Isabo Odeda Ibara Coker Fidiwo |
| Ibadan | Ijaiye-Orile Iressi Obada Egbeda, Oyedeji |
| Ijebu | Ilishan Ogegbolu Atan Imope Ishan Isara Imodi Ajegunle |
| Ijesha | Ilase Epe Iloba Iperindo Imaroko Erinmo Esa Oke. Iloko. Eti-Oni |
| Ondo ati Eti Odo | Agirifon-Ilutitun |
| Egbado | Aiyetoro Tata Randu Ado-Odo |
| Ogbomosho | Iressa-Du Arolu Egbeda Jabata. Oke Imale |
| Ekiti | Egosi. Odo-Aiyedun. Okemesi |
| Ibinni | |
| Delta | Kokori |
| Igbajo | |

### OJỌ 'BỌ 1ST AUGUST (WEDNESDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Mushin, Badagry |
| Abeokuta | Otta Abalabi Sodeke. Omida Ilawo Owowo, Obafemi. |
| Ibadan | |
| Ijebu | Ikenne, Okunowa, Erunwon, Ibefun, Atikori, Imusin, Ijesa-Ijebu, Omu, Mojoda Ago-Iwoye, Ijagba-Ayeni |
| Ijesha | Ijebu-Ijesa, Osu, Itagu Idoko, Idoka, Iloko, Odogbo |
| Ondo ati Eti Odo | Isbua |
| Egbado | Ilobi, Igbogila, Ijoun Imasai |
| Ogbomosho | Araromi, Iregba |
| Ekiti | Erekesan |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | Iloro |

### OJỌ 'RU 2ND AUGUST (THURSDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Agege, Ikeja |
| Abeokuta | Lafenwa, Obada, Oba, Kajola, Ajegunle, Idogo, Ilori, Ogumaki |
| Ibadan | Lalupon |
| Ijebu | Isara, Imodi, Mamu, Ipara |
| Ijesha | Esa Oke, Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-Odo |
| Ondo ati Eti Odo | Igbo-Egunren, Atijere, Oni, Ebiwo. |
| Egbado | Idi-Oni, Lasilo, Igan-Okoto, Atta Oko. |
| Ogbomosho | Ifaki Okemesi. |
| Ekiti | Uromi. |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | |

### OJỌ ẸTI 3RD AUGUST (FRIDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Oyingbo, Ejigbo |
| Abeokuta | Ijoko Iberekodo Asa Wasimi |
| Ibadan | Ogunjana Lagun Sagbe |
| Ijebu | Aiyepe Sasanu Ilasa Oere Irolu Ilele Ita-Iloti Oyingbo, Oru Ita Aganda |
| Ijesha | Ilesu-Ilesha Imodi Ibode Kajola, Oluwa'da, Ita-Apa |
| Ondo ati Eti Odo | Oka Ilara |
| Egbado | Alagbo Ilaro Sunwa Iboro Jiga |
| Ogbomosho | Obada Gambari |
| Ekiti | Ilogbo Oke-Aiyedun Idogun |
| Ibinni | Eke |
| Delta | |
| Igbajo | |

### OJỌ ABAMẸTA 4TH AUGUST (SATURDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Obun Eko |
| Abeokuta | Atan Agbado Ifo Itoko Isabo Odeda Ibara Coker Fidiwo |
| Ibadan | Ijaiye-Orile Iressi Obada Egbeda, Oyedeji |
| Ijebu | Ilishan Ogegbolu Atan Imope Ishan Isara Imodi Ajegunle |
| Ijesha | Esa-Oke Ilase Epe Iloba Iperindo Imaroko Erinmo Iloke |
| Ondo ati Eti Odo | Odojomo Igbotako Ilepan Obonkekere Agirifon-Ilutitun |
| Egbado | Aiyetoro Tata Randu Ado-Odo |
| Ogbomosho | Iressa-Du Arolu Egbeda |
| Ekiti | Egosi, Odo-Aiyedun |
| Ibinni | |
| Delta | Kokori |
| Igbajo | |

### OJỌ AIKU 5TH AUGUST (SUNDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Mushin, Ebute Ikorodu. |
| Abeokuta | Owode Otta Abalabi Sodeke. Omida Ilawo Owowo Obafemi |
| Ibadan | Oja-Oje. |
| Ijebu | Ikenne. Okun-Owa Erunwon. Omu Ibefun, Atikori Imushin, Ijesa-Ijebu, Mojoda Ago Iwoye, Ijagba-Ayeni |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha Osbu Itagu, Odogbo, Idoka, Iloko, Ipetu |
| Ondo ati Eti Odo | Agbabu, Igbosi, Ishua, Erinketa |
| Egbado | Olorunda, Kajola, Ilobi, Eredo |
| Ogbomosho | Araromi, Iregba |
| Ekiti | Erekesan. |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | Iloro. |

### OJỌ AJE 6TH AUGUST (MONDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Agege, Ikeja, Ebute-Ero, Ojo. |
| Abeokuta | Lafenwa, Obada, Oba, Kajola, Ajegunle, Idogo, Ilori, Ogumaki |
| Ibadan | Ibuko, Lalupon |
| Ijebu | Isara, Imodi, Mamu, Ipara |
| Ijesha | Esa-Oke, Iwara, Ejioro Odo, Ibokun, Esa-Odo, Ijeda, Ikeji. |
| Ondo ati Eti Odo | Igbo-Egunren. |
| Egbado | Idi-Emi, Ibesine, Lasilo, Atta Oko. |
| Ogbomosho | Ifaki Okemesi. |
| Ekiti | Uromi. |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | |

## Prophet Anjọrin komọjade

IPONRI VILLAGE

NI ọjọ Ọjọbọ ti ọsẹ ...ọjọ karun oṣu yi ni Prophet A. P. Anjọrin ti Ijọ Ẹgbẹ Serafu ati Kerubu ni 29, Western Avenue, Iponri Village, ṣe ẹyẹ ikomọjade ọmọbirin ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ, Iyaafin Agnes Oladiti Anjọrin lọre. Gbogbo ẹbi, ijọ ati awọn ọrẹ ni pejọ sibẹ ... awọn ṣe oruko fun ọmọ na ni Deborah Iyabode Olufunmike. Ki Olu... jẹki a mọ o mọ oruko ...

Ẹniti o ṣe eto isomo'ruko na ni Baba Aladura gbogbo agbaiye S. A. Anọdu, ẹniti o ṣe alaga ayẹyẹ isomo'oruko pẹlu ni Pastor J. A. Oki, ọkan ninu awọn aṣiwaju Ijọ Ẹgbẹ Kerubu ati Serafu. Diẹ ninu awọn oni-pawu ọjọ na ni Ọgbẹni Amos Oni, Ọlabiju Anjọrin, Iya Ijọ Ọlagunju pẹlu gbogbo Ẹgbẹ Ijọ Kerubu ati Serafu Ọrangun ati awọn Ẹgbẹ Aro Ibile Ipẹtu-aro-Ọdo, nwọn si nawo na'ara.

Ẹyẹ ọjọ na dabi ọrọ Ifiiran Jesu Olugbala ti O sọ pe "Ohun rere kan ha le ti Nasarẹti jade wa? E jade ki ẹ wa wo o..." Ki Ọlọrun da ọmọ na si ki O si fi iru ayọ yi fun gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na.


**Iwora Lakuregbe**

NIBIN NI IDERA GAN AN WA

[illegible]

De Witt's Pills jẹ egbogi ti ... [illegible]



IJẸRI SI WA

Egbogi De Witt's Pills ... [illegible]

DE WITT'S PILLS

for Kidney and Bladder Troubles

# IDI TI IJỌBA FI YỌ OLOBI L'OYE

Lati ọwọ ewe kini

... eto ofin ti se lo ni nwon ... fi yọ ẹ l'oba nitori eyi ... agbara.

Adebọwale ni gbogbo agbara re lati je ọkan ninu Igbimọ Ijọba Ibilẹ Egbado-Ilọnju ninu ọdun 1954, sugbọn awọn afa ilupaapa awọn Ijoye ati olu ilu ti ake kori, nwọn ko gba fun un. Bi o ba se pe awọn Igbimọ na gba a ni ni Ijọba le fi ni ọwọ si i, sugbọn nigbati nwọn fi ake kori pẹlu idi nitori ti o fa a Ijọba ko le fi tuinsi inu wọn lati gba Adebọwale sinu Igbimọ wọn.

Ni ọjọ keta osu keji ọdun ti o koja yi ni Ajele Agba kowe si Alabojuto Ise Idajo ati Igbimọ Ijọba Ibilẹ pe iwa Adebọwale buru to be ose de aye ti o fi yẹ ki nwọn yọ ọ l'oba ki nwọn si le e kuro ni ibi ati kuro ni agbegbe ilu Egbado, eyi mu ki Ijọba o beresi se iwadi pelu iranwo Olola Adegbenro lori imoran na ni.

Ni agbonjo osu kinni ọdun yi ni awọn ijoye ti wọn fi ọwọ so aiya pe awọn ni afọbaje (kingmakers) Ilobi ko iwe ẹbẹ si Ijọba Ipinle Iwo-Orun lati yọ Oba Adebọwale gegebi asa isedale. Ninu iwe ẹbẹ na nwọn fi han pe awọn fẹ ki Ijọba Ipinle Iwo-Orun ni ọwọ sinu ife wọn na. Nigbati Alamojuto Ise Idajo ati Igbimọ Ijọba se iwadi finnifinni pelu iranlọwọ Olola Adegbenro o ri pe af'obaje ni awọn ijoye na ti ododo ati pe nwọn ni agbara ati ẹto lati yọ ẹ.

Lori gbogbo ẹri iwa aidana ti Oba Adebọwale nhu ti o di gbigbọ fun gbogbo enia ni o mu ki Alamojuto Idajo ati Igbimọ Ijọba fi ri si pe nwọn le fi ofin isedale yọ o kuro l'ori oye Oba ati pe o tọ ki nwọn le e kuro ni ilu fun alafia ati idagbasoke ilu na gegebi Ajele-Agba ti fia a ni imọran. Eyi ni o mu ki Ijọba fi yọ ọ loye patapata.

Alabojuto yi kọ ti gba pe ki nwọn le kuro ni agbegbe Egbado, sugbọn nwọn ti se ikilọ fun un pe ki o mase hu iwa ti yio tẹ ofin Ijọba loti de aye ti ilu yio ti fe dara ati pe ti o ba se bee, kele yio gbe e. Ijọba ko ni jeki o wa ni agbegbe Abeokuta mọ.


# ẸNYIN AGBẸ ONIKOKO Ẹ RANTI



***Ja gbogbo apopo koko ti o ba bajẹ kuro ki ẹ si ma a ri wọn mọlẹ ki ẹ si ma a fun***

**'PERENOX'** TABI **'PEREPOD'**

***s'ara igi koko l'ọsẹ kẹta-kẹta***

**Ki arun korikori ma ba a gbe Koko ati Owo nyin lọ**

Ninu awọn Garawa oni iwọn ẹsun merinla (14 lb) ni "PERENOX" wa
tabi
Ninu awọn Garawa oni iwọn ẹsun meji (2 lb) ni "PEREPOD" wa
Pẹlu ọsuwọn ati iwe apejuwe kekere l'ọfẹ
Didi ni awọn Garawa ogun na wa lati ri i daju pe nwọn wa ni ẹkun rẹrẹ ati pe ko ma fi le bajẹ rara.
Kö na enia ati awọn Ẹranko l'ara bi nwọn ba lo l'ọna t'nwọn se apejuwe lilo rẹ

O wa kakiri ẹka ile isẹ ati lọdọ awọn aṣoju
THE COOPERATIVE SUPPLY ASSOCIATION
tabi
THE UNITED AFRICA CO. LTD

**Plant Protection Ltd.**




# Yiyan Gbadegẹsin ni Ọba tọna

Lati ọwọ ewe kini

Ladigbolu w'aja nitori idi eyi. Bello Gbadegesin gbodo je Oba ni nitori on ni o tọ si nitori on ni o si kan. Ẹyẹ ti eto-oye Oyomisi, agba-oye ni Babayaji, sugbọn Bashorun ni asiwaju gbogbo oloye Alafin, ati wipe awọn Oyomisi ti o yan Bello Gbadegesin je ojulowo Oyomisi ti a mọ.

O ni Oyomisi ni Alapini, sugbọn labe Oloye Babayaji ni, Onamodeke ni adugbo re, bakanna ni Shamu je Ologe abe Bashorun, o ni nigbati ologbe Ladugbolu w'aja, gbogbo Oyomisi lo wa lẹhin pe ki Bello Gbadegesin je Oba dipo baba re, sugbọn nitoripe Bashorun ko gba imoran wọn ni o je ki nwọn da Bello Gbadegesin duro lati gun ori Ite Alafin Oyo ni nwọn ba fi yan Alhaji Adeniran Adeyemi Keji ti Ijọba to e loye yi.

## Ẹ tun Aiyetoro ṣe

AIYETORO, Egbado je ilu ti o gbooro ti o si lokiki, ki i tapa si ofin Ijọba rara. A bẹ Ijọba fun awọn titi ọlọda ati ẹrọ asoro-magbesi. A ni mimọ pe laisi owo, nkan wonyi ko le sese. Nitorina ni awa ara ilu yi ki i se fi owo-ori jafara, a ma a nsan an l'asiko-l'asiko ni. A nreti o.

Emi ni,
Yesufu Akanbi Adedigba.
Ketu-Aiyetoro,
Egbado.

## Ilu Erinmope nfẹ Titi-Ọlọda

INU mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye lati bẹ awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun pe ki nwọn jọwọ ranti ilu wa fun gbogbo inkan ọlaju ti nwọn nse kakiri awọn ilu abẹ Ijọba Ipinle Iwọ-Orun.

A nfẹ Ile Adajọ (Kotu), omi-ẹrọ ati pe ki ẹ ba wa gbe titi-ọlọda ti nwọn se lati Akure de odo wa koja si Ipinle Ilorin. A dupe nipa Ile Iwe-ọfẹ f'awọn ọmọde ti Ijọba dasilẹ. A si ngbadun rẹ nisisiyi, ọwọ a ma a r'oke o.

Emi ni,
JOHNSON B. AJIBOYE
Ilorin.

## Ẹ tun Titi Idi-Ogun ṣe

LAISI ani-ani, Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nse eto idagbasoke awọn ilu ti o wa ni Ipinle Iwọ-Orun dada, a si ti ri ọpọlọpọ ise ribiribi ti Ijọba na tise. Sugbọn anu se ni lati so pe Titi Idi-ogun lẹba Oleruma, Ibadan, ko dara rara, koto ati igbo pọju nibẹ. Ki Ijọba gba wa lati ri pe a bori titunse. A dupe o.

Emi ni,
Joseph Akinbola Adelanwa
Ibadan.

Printed by the Amalgamated Press of Nigeria Ltd. Editor: S. M. Adeniyi... 5/7 Apongbon Street, Lagos. Chapel Street. Lagos.

# Iwe si Olotu Irohin Yoruba

## Ę fun wọn l'ękọ

O JĘ ohun iyalęnu fun mi pe opolopo awon ara igberiko Ipinlę Iwọ-Orun ni nwọn ko jęki awọn ọmọ wọn lọ si ile-iwe ọfę ti Ijọba Ipinlę Iwọ-Orun fi da wọn lọla. Tęlętęlę ri ogoro ni o ti nsọ pe ko si owo lọwọ en lati fi san owo ękọ ọmọ on, ṣugbọn Ijọba ti so eyi d'ęrọ nisisiyi.

Iyatọ nlanla ni o wa larin ęniti o ka iwe pęlu ęniti ko ka rara, awọn ọmọ'we ni i di Minista, ni nwọn ndi ęni iwaju ṣugbọn awọn alaimọkan ki yio le de aye nlanla yi, abamọ si ni fun awọn ọmọ na lęhin ọla.

Mo dupę aye ti Olotu gba mi.

Emi ni,
Z. Olu ABỌDERIN.
Abęokuta.

## Ko si ọna nibę

O JĘ ohun ti o yani lęnu lati ri ka ninu iwe nyin ti 25.6.56 pe awọn ęgbę kan ti a npe ni "The Lagos State Movement" eyi ti Ogbęni T. O. S. Benson ję baba-ęgbę fun nfę ki Eko, Badagiri, Ejinrin, Ikorodu ati Epe da wa po, ki nwọn ma si labę aṣę Ipinlę Ijọba Iwọ-Orun.

Gbogbo wa l'a mọ pe pataki kan ni Ogbęni T. O. S. Benson ję ninu Ęgbę Alakuko (NCNC). A ko ri iṣę atata kan ti ęgbę na a ṣe fun ilę Yoruba. Ko yę ki ojulowo ọmọ Yoruba ka ọrọ rę ati ti awọn ęgbę rę si mọ, ko si ọna ninu eyi ti nwọn gbe kalę yi. Ę maṣe fi eti si wọn rara.

Eko, Badagiri, Epę, Ejirin ati Ikorodu, ilę Yoruba ni nwọn nṣe lati iwaṣę. Ninu Ipinlę Iwọ-Orun ni nwọn gbọdọ wa.

Emi ni,
E. A. LADAPỌ.
Kafanchan.

## Ki Ijọba maṣe gbagbe Ijabę

A RI i dajų pe Ijọba Awolowo ti ṣe gudugudu fun idagbasoke Ipinlę Iwọ-Orun, nwọn si tun nṣe awọn iṣę ribiribi lọwọ fun Ipinlę na pęlu. L'otitọ a ri i pe awọn iṣę wọn ti pọju, ṣugbọn a bę Ijọba na ki nwọn maṣe fi ọrọ ilu wa, Ijabę fulę.

Ilu wa nfę ignitiriki ati titi olọda, nitoripe a mọ wipe laisi owo, awọn nkan wọnyi ko le ṣe, ni a fi nsan owo-ori na deede. A o dupę ti Ijọba ba le tete ba wa ṣe ẹ̀ṣe awọn nkan wọnyi fun idagbasokę ilu wa.

Emi ni,
HAMEED M. A. ONI.
G.P.O., Sammebọ

## Mo gbadun iṣę Ęgbę Afęnifęre

LATI nkan bi ọdun meje s'ęhin, ki o to di igbati Ijọba bọ s'ọwọ Ęgbę Afęnifęre l'akoko ni awa ara Igboho ti nṣe wahala ilọsiwaju ilu wa funra ra wa, bę ę la a kọ ile-iwe ati ile iwosan. A si nsan owo-ori wa deede.

Sibę-sibę lati igbati Ijọba Ipinlę Iwọ-Orun ti bọ s'ọwọ Ęgbę Afęnifęre ni anfani nla orişiriṣi ti nwọ ilu wa lati ọdọ Ijọba. A dupę lọwọ Ęgbę Afęnifęre fun anfani wọnyi.

A si tun bę Ijọba ki nwọn fun wa ni Posu Ofisi ki awa ti a wa ni idalę le ma a je anfani ilu wa.

Emi ni,
A. A. ADEDIGBA.
Sawla lęba Bole,
Gold-Coast.

## Ęgbę Alakukọ sin Adeniran de'bę

APOTI awọn Alakukọ ti ṣe alakara kabiawu na. Awọn alagidi ti Alhaji Adeniran Adeyemi de ibiti nwọn fę. Kini ekę ti a ri kọ ninu ọrọ yi? Ohun ti suuru ba ṣe ti ęhin aro ni yio gbe. Mo bere bi alaimọ, nibo ni awọn onimoran Adeniran wa loni? Nibo ni awọn ọrę apapadodo Adeniran wa loni? Gbogbo ohun ti nwọn leri leri pe ko ni i ṣe loju ęmi awọn ni nṣe wọnyi. Nwọn ti yọ Adeniran loye na. Oba Belo Gbadegesin si ti bọ si ipo baba rę, ọba ti ti oje bo olorisa lọwọ na, o wa ku baba ęniti yio bọ ọ.

Emi ni,
ESTHER GBADEŞIRE.
Akęsan, Oyo.

## Aikodun ọsan ni a ngmu'kan ṣoṣo

NIGBATI mo ri i ka ninu awọn iwe *Irohin Yoruba* ti o jade ni ọjọ kętala oşu keji ọdun yi, ati ti ọjọ kejidinlogbon oşu karun ọdun yi ti awọn Ogbęni Sunday Kano ati Otemuyiwa Ogunlabi kọ pe ki iwe *Irohin Yoruba* ma a jade l'ękanşoşo ti nwọn si ṣe alaye bi o ti ṣe to loju wọn, sibę na mo lodi si imoran wọnyi lori idi wọnyi.

Ọna kinni, mo fę ki ę ranti pe gbogbo iwe ti nwọn ntę l'ede Gęęsi ojojumọ ni nwọn njade lai da ọjọ kanṣi, omiran ti le njade l'ęmeji l'ojumọ, ti nwọn si nsọ bi gbogbo inkan ti nlọ si ni ilu ilu ko ba awọn ti nka a. Ọna keji nipe iwe *Irohin Yoruba* yi ti dun koja lękan l'ọsę lọ, o nfi ogbọn kun ogbọn, o fun wa l'oye kun oye, o si nsọ ęni-ęhin d'ęni iwaju, awọn agbalagba ma a npe l'owe pe "Aikodun ọsan ni a fi ngmu 'kan ṣoṣo."

Nitorina bi ę ba le jęki o ma a jade l'ęmęta tabi ti ojojumọ yio da a pọpọ.

Mo dupę aye ti Olotu gba mi o.

Emi ni,
HAMEED YAKUBU.
Ikirun.

## Tanwiji pọ nibę

EYI ni lati mu wa si iranti awọn oşelu Ęgba ati Ijọba Ipinlę Iwọ-Orun pe Odo Adagun ti a npe ni Şegudu buru tobę gęę ti o fi ję wipe ęęgn ati tanwiji ngba yun loju rę—ko si jęki awa ti o wa ni Oke-Odo gbadun.

A ję pa ni ęęgn nję enia ni Oke-Odo.

Inu mi yio si dun ti awọn oşelu wa ba le fi si ero, ki nwọn si mọ ọna ti omi yi ko fi ni darogun.

Emi ni,
J. O. SHOYINKA.
Oke-Odo,
Ifọ.

## Ę layi ye wa?

INU wa yio dun bi ęnyin onkawe *Irohin Yoruba* ba le ṣe alaye ibere yi ye wa: Nibo ni a ti nri irin (iron) ti a fi nṣe ọkọ tabi ada ki awọn Oyinbo to de Naijiria, tabi Olorun ti da a silę kakiri aiye ni?

Mo dupę aye ti ę gba mi o.

Emi ni,
S. A. ADETOYI.
Pramkese, Gold Coast.

E MAA KA IWE IROHIN YORUBA NIGBAGBOGBO

AWON OGBOLOGBO
(SCRAP)
OJE (LEAD)
IDẸ (BRASS)
BABA (COPPER)
AWỌN ALOKU IRIN
ẸRỌ MỌTO (RADIATORS)
PAANU AYỌ (ALLUMINIUM)
JẸ OWO
Ko wọn wa ta fun
BUCK (NIGERIA) LTD.,
2, AERODROME ROAD, APAPA.
TELEPHONE
55177.



# IPIN AWON ELEGAN

IBADAN je ilu pataki ni ile Yoruba. Ipo ilu na ni o so o di nla. Akikanju awon enia inu re je okan ninu ohun ti o so o di nla. Iwaju ni awa omo Ibadan ba ilu Ibadan. Iwaju na ni awon baba wa ba a. Kini awa nse lati fi i si ipo iwaju yi ati lati ri i pe o ndagba ni ipo na?

Ana se mi lati sakiyesi wipe pupo ninu awa omo Ibadan ko du lati fi kun ola ati ogo re. Yoruba a ma a so pe: "orisa bi o le gbe mi, se mi bi o ti ba mi." Awa omo oni ko fi kun ola Ibadan, a ko si fi Ibadan sile bi a ti ba a, a nbu ola ilu na ku ni. Ona wo ni a fi nse eyi?

Ko si ilu kan ni ile Yoruba ti ola e po to Ibadan. A ko gbodo tan ara wa je. Ni akoko ogun ati ote, iwaju ni awon baba wa wa. Ko si ogun mo. Ko si ote mo. owo ati eko ni nwon fi nsaiye loni. Nibo ni awa omo Ibadan wa ninu nkan wonyi? Ehin ni a wa bi a ko ba ni tan ara wa je. Oju ana ni pupo ninu awon omo wa fi nwo oni iwa janduku [illegible] pe mo. Iwa wompari ko so enia di okunrin mo, elewon ni nso won da.

Awon Ijesa ni nwon ni ogunlogo moto-takisi ti o wa ni ilu Ibadan. E wadi wo, e o si ri i bee. Emi ko ba won wi. Ise ni oogun ise. Owo awon omo Igbajo ni owo pako ilu Ibadan wa. Eyiti o po ju ninu awon ile daradara titun titun ni ilu Ibadan ki i se ti awon omo Ibadan ti awon Ijebu ni. owo ni awon omo Ogbomoso nse. Onise ati olowo gidigidi ni awon Ijebu. Awon Egba ko kere ninu ise Oba ati ise owo sise.

Kini awa nse ni ilu Ibadan? Ile wa dara fun koko. Melo ninu awon odomokunrin wa ni nwon duro ti oko? Bi o ba fe ja iro mi, rin kakiri ilu Ibadan lakokokakoko ti o ba fe, ki o si ka iye odomokunrin ti o ri ti nwon ko ni igba ise kan.

Kini awon odomokunrin wa nse? Nwon nso wipe awon nse ilu. Itanje kan ko ju ti enitit ko le toju ara re ti o so pe on yio toju odidi ilu lo. Ogunlogo won ko ko kewu, nwon ko kowe, nwon ko si ni ise lapa. Arun nla ni nse ilu Ibadan. Ona wo ni a o fi wo arun buburu yi san?

## Lati owo OMO OKE'BADAN

Awon elero kukuru ninu nwon omo wa a ma a binu awon Ijebu. Kini mu ki awon Ijebu ma a ko ile kun'le? Nwon ko se ole ni. Nwon nkowe, nwon nsowo, nwon ko jafara. Kini awa nse? Kini se ti awon Ijesa fi nlesiwaju? Ise dun [illegible] lapa ni. Kini awa nse n'ilu Ibadan? Pupo ninu awon odomokunrin wa nfi eta inu so ara won di ota awon ti nsise. Nibo ni eta inu yi yio gbe wa de?

Awon omo Ibadan ti nwon ko fe ise se wonyi so ara won di ota awon egbon ati aburo won ti nse ara won lati sise. Eebu ti a nbu won ko pe ki awon Ijebu ma lowo lowo mo. Eebu ti a nbu Ijesha ko gba moto takisi kuro lowo awon Ijesa. Eebu, egan ati etanu yi ko ti i so enikeni di olowo larin awon omo Ibadan. Oro wa fe ayewo.

E ko sinu Egbimo Asofin l'Eko tabi ni Ibadan. Iru awon etita wo ni Ibadan ni nibe? Awon onowe melo ni a ni nibe? Iru awon ti o ti Abeokuta wa ni a ni? Ki ise bee. Etanu ni a fi ko awon ti yio gbe wa niyi sile ti a si nu awon begbee enia. Eyiti a nse ni ona ise ati ni ona owo na ni a fun gbe wo inu oro isele. Oro wa fe irenu.

Imoran mi ni pe mo fe ki gbogbo awa omo Ibadan ni Egbimo apero pataki ninu eyiti a o gbe ye awon arun ti nse wa wo ti a o si ronu ona ti a o fi wo arun na san. Ipade apero yi ye ki o si sile fun gbogbo omo Ibadan l'okunrin l'obirin laikoinu iru egbe oselu k'egbe oselu ti oluware le wa. Mo be gbogbo awon agbaagba Ibadan ki nwon ti mi lehin ninu imoran yi. Awon ni mo si be wipe ki nwon se okunfa lati pe ipade na. K'Olorun ma fa wa sehin. Eyiti o ju ni ki awa paapa mase fa ara wa sehin ninu are Ije ti gbogbo aiye nsa loni fun ominira ati ninu ilosiwaju ninu ohungbogbo ti o je rere.

**E ma a ka Iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun**

# Are Di Baba Egbe Obirin Oloja

EKO

ESE awon obirin onisowo pataki pataki Eko ati ti Ebute Metta ni o pe soso, nwon fere to edegbata (5,000) enia si ile Oloye-Hadja Rabi Alaso lati fi Oloye Kansilo Teslim S. Abiodun Fujah, Are Eko je babaegbe won ropo Oloye T. A. Omosola Savage.

Lehin ti awon ti je oye na tan ni oloye na ko awon alabaseye ojo na lo si ile re Ile Ola Chambers 43, Docemo Street, o si fi orisirisi onje adidun ati orisirisi oti te gbogbo awon alabaseye ojo na lorun titi ile ojo keji fi mo; ijo ojo na po, Irohin ko to afojuba ni eye ojo na.

Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon enia pataki pataki ti o pe sibe ni Oloye Ilaola Odibo, Oloye Modile, Oloye Onisemo, Oloye Asogbon, Oloye Suenu, Oloye Faji ati Ogbeni Y. Ayinla Disu.

O ye a mo'ri o.



KANSILO T. S. FUJAH, ARE EKO









## Olu Odi-Olowo dupẹ

ODI-OLOWO—EKO.

ESE gbogbo Ẹgbẹ Ọmọ Ẹgba ni Mushin ati agbegbe rẹ ni o pe si Ṣọọṣi St. Peter U.N.A., Odi-Olowo, ninu oṣu kẹta ọdun yi lati ba Kansilọ Samuel Adewunmi Adewusi Adelẹyẹ ṣe idupẹ fun Oye Olu Odiolowo ti nwọn fi i jẹ. Ẹṣọ ti Olu na ati awọn ijoye rẹ ṣe kọjọ na pabambari.

Alufa J. O. Atowoju ni o ṣe akanṣe iwasu isin idupẹ na, iwasu rẹ dun pupọ. O yọ ẹsẹ wura rẹ ọjọ na lati inu awọn Ọba Kinni 3: 9. Alufa D. B. Taiwo ti Ijọ C. C. Mission ni o ṣe adura pataki, lẹhinna Olu na, awọn ijoye rẹ ati awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na si mu ọrẹ wọn wa siwaju pẹpẹ. Oloye Salami Koledoyẹ, ọkọ Wule Oyinbo, iya Taju dabira lọjọ na.

Bi nwọn ti njade ni Ṣọọṣi na ni nwọn ti mba Oloye na ko ẹyẹ lọ si Afin rẹ, o si fi oriṣiriṣi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo wọn lọrun titi ilẹ ọjọ na fi ṣu. Inawo ọjọ na buaiya o le gongo. Oye a mọ'ri o.

## Aderonkẹ sin iya rẹ

OSHOGBO.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejo oṣu yi ni iya oninure, Aṣiawu Aderonkẹ sin oku iya rẹ. On ati awọn ọmọ oloku yoku fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun titi ilẹ fi ṣu.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu wọn ni awọn Ọgbẹni Yesufu Adebiyi, Lamidi Ajagbe, Sunmọnu Adisa, Raimi Arẹmu, awọn Iyaafin Aṣiawu Aderonkẹ ati Afusatu Abikẹ. Ki Oluwa fi awọn ọmọ irẹ gb'ẹhin awọn ọmọ oloku na o.

## Ẹgbẹ Ilupẹju ọmọ Ẹdẹ ṣe inawo

KANO.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ogunjọ oṣu karun ọdun yi ni Ọgbẹni Yaya A. O. Lawal, olori Ẹgbẹ Ilupẹju Ọmọ Ẹdẹ ti Kano ṣe inawo Ajọdun *Sunday Ọdun* ni ile rẹ ni 39, Middle Road, Sabon-gari, Kano. Nibẹ ni ẹsẹ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ati awọn alabaṣẹyẹ wọn pe si, ti nwọn si yọ ayọ ajọdun na titi ilẹ fi ṣu.

Ọgbẹni Alimi Lawore (Akapo Ẹgbẹ) li o ṣe adura, o gbadura fun Olori-Ẹgbẹ, Yaya A. O. Lawal ati gbogbo ọmọ ẹgbẹ, paapa julọ fun ilu Ẹdẹ pe ki Ọlọrun jẹ ki ilu na tubọ ni ilọsiwaju. Ajọdun na larinrin fun jijẹ ati mimu, ijo ati ayọ, nwọn si ya fọto papọ ni irọlẹ. Aṣeyi ṣ'amọdun o.

## Oloye Fujah ṣe ikomọ

EKO.

ESE awọn ijoye ati awọn enia pataki pataki miran ni o pe ṣọọ si "Ile-Ọla", 43, Docemo Street, ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kọkandilogbọn oṣu ti o koja yi lati ba Atọtileto Oloye T. S. Abiọdun Fujah, Arẹ Eko ati Iyaafin rẹ, Sariyu Fujah yọ ayọ ọmọ. Ọmọ wọn, Iyaafin J. O. Adenẹkan bi ọmọbirin arẹwa kan si Londonu. Nwọn so ọmọ na ni Fọlaṣade Adetokunbọ.

Oloye Gbadẹgẹre Ọgabi ni alaga l'ọjọ na. Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Oloye Mohmoh Batula, Modilẹ Eko, Oloye Tawaliu, Onisẹmọ Eko ati Oloye Sulu, Aṣogbọn Eko.

*Ki Oluwa ṣọ ọmọ na ati awọn obi rẹ bọ wa'ile, ki O ṣe wọn ni olori ire, ki O si fi ire kari o.*


## Kiniṣe ti inu awọn Ẹbi Ogbe* fi ma a ndun!






# OVALTINE

*—ko si ohun ti o dara to!*


## OLOYE ỌBANIKORO MỌ ỌMỌ-MO RE



L'ẸNULỌLỌYI NIGBATI Ọgbẹni Emanuel Olu. Adebanjọ, oniṣowo pataki Eko ati aya rẹ ẹlẹyinjuẹge, Mobola Ogunlana, ọmọ Oloye Ọbanikoro Eko, nṣe ikomọjade ọmọ ọkunrin ti Ọlọrun fi ta wọn l'ọrẹ ni nwọn ya aworan oke yi fun iranti ojo na. Lati owo osi, e o ri awọn Ọgbẹni Abdul Wahab Balogun, Emanuel Olu. Adebanjọ, Oloye T. S. Fujah, Arẹ-Ọnakaka Eko, awọn Ọgbẹni Yek. Ọmoyayi Alebiosu ati Y. Ayinla Disu. (Bigman)


*F maa polowo ọja nyin sinu iwe*

**IROHIN YORUBA**

*ki ẹ si tun maa ka iwe na fun irohin aladun nigbagbogbo.*



No. 105.

**Vacancy for Museum Technical Assistant.**

Applications are invited for the post of Museum Technical Assistant in the Antiquities Service. Further particulars in Government Notice No. 811 published in Federation of Nigeria Official Gazette No. 31 dated 3rd of May, 1956. Application to Surveyor of Antiquities, Nigerian Museum, Lagos. Closing date 31st August.

